Ododo ni i gbe Orilẹ-Ede leke.

# Irohin Yoruba

VOL IX No 461 MONDAY MAY 10, 1954 KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja nyin sinu iwe Irohin Yoruba

# Action Group Youth's Association S'Ajodun

EKO- Ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kejidilọgbọn oṣu ti o kọja yi ri ẹsẹ awọn Ẹgbẹ Ọdọ Action Group (Action Group Youth's Association) pe ṣọṣọ si Campos sqare, nwọn to lati ije Baba Ẹgbẹ wọn Dọkita Akanni Doherty nwọn pọ to ẹgbarun enia. Bayi ni nwọn ṣe to lọwọ de Campos Sqare nwọn nlu nwọn njo kakiri gba ọna adugbo pataki pataki ni Lafiaji, ọpọlọpọ enia si ti rọgun sibẹ de wọn ni Campos Square lati ba wọn ṣe ajayọ na.

Nigbati awọn Ẹgbẹ Ọdọ na njo kakiri nwọn gbe awọn asia orisirisi dani nwọn kọ awọn ọrọ isiri orişirişi si ara awọn asia na lori ọrọ Ijọba ilu Nigeria pe a gbọdọ tete gba ominiran na ni ati pe ko si ọna nibẹ rara lati ya ilu Eko kuro lara awọn ilu abẹ Ijọba Iwọ-Orun Nigeria ati pe ki Ọlọla John Stuart Macpherson Gomina Nigeria ma ṣe jafara lati wọ Ẹgbẹ Action Group. Awọn Ẹgbẹ obirin ọloja ba wọn jo kakiri lẹjọ na.

Nigbati nwọn de Campos Square ni Ọgbẹni R. A. Pani-Kayọde Alaga Apapọ Ẹgbẹ Ọdọ Action Group na tẹnumọ nigbangba pelu ifẹ ododo pe gbogbo awọn Ẹgbẹ Ọdọ Action Group ni awọn ni igbekẹle si Ọlọla Obafẹmi Awolọwọ pe o to aṣiwaju Ẹgbẹ Action Group ṣe ati pe o si nṣe daradara, awọn si wa ni alatilẹhin fun un d'ọla.

Ninu ọrọ rẹ o fi han pe asiko ti awọn ni lati ma a se ijọba ilu awọn funra ara wọn ti ṣẹ nto ati pe awọn ko si le wa labẹ ajaga ijọba ilu miran titi laelae. O ni nigbati awọn ti ṣe ipinnu pe awọn yio kuro labẹ ajaga ijọba miran ko si ohun ti o le yi ipinnu na pada mọ.

Ọgbẹni S. A. Adebanjọ Akọwe Apapọ Ẹgbẹ Ọdọ na sọ pe awọn Ọdọ ko ni gba pe ki a fi akoko gbigba ominira ilu Nigeria o falẹ ju ọdun 1956 lọ.

Oloye S. L. Akintọla si sọ ọpọlọpọ ọrọ iwuri ati ohun ti o tọ fun gbogbo wa lati ṣe ki ominira to le bọsi fun wa pẹlu irọrun.

Ajọdun na dun o larinrin, irohin ko to amojuba ni.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn enia pataki pataki ti o pe sibẹ lọjọ na ni awọn Oloye Dọkita Akanni Doherty, S. L. Akintọla, J. A. Ajao, Oloye Fusigbuwa Ikorodu, Ọlọla A. C. Williams, Ọgbẹni S. L. Ayẹni ati Iya Ẹgbẹ Oja Ebute Mẹta.

# OBA ADELE T'AJO DE

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu yi ni Alaiyeluwa Adeniji Adele Keji Ọba Eko pẹlu awọn Ijoye rẹ ti o ba a lọ de si Eko, lati ilẹ Hausa ti o ti lọ fun pipe ti Sardauna Sokoto, Alakoso Igbimọ Aṣoju Ijọba Iha Ariwa (Ilẹ-Hausa) pe e wa, fun ẹyẹ isile Ile Ẹkọṣẹ awọn onişẹ ọba (Institute of Administration) ti nwọn ṣẹṣẹ kọ si Zaria.

Ki Ọba na to pada si Eko pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ, nwọn se ibẹwo Kano ati awọn ilu pataki ti o wa ni ilẹ Hausa, awọn Ọba Hausa ti o jọba ninu awọn ilu gbogbo ti nwọn de ni nwọn gba wọn tọwọ-tẹsẹ pẹlu gbogbo Ẹka Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ti o wa lọhun pẹlu gbogbo Ẹgbẹ Ọmọ Yoruba ti nwọn rgbe ibẹ.

Nigbati o ti ku bi wakati marun ki Ọba ra gunlẹ si Eko ni ogunlọgọ awọn enia ati awọn obirin ti o ngna ọja ti pa ọja nino ti si gbogbo wọn si lọ pade rẹ pẹlu orisirisi ilu, ti nwọn to lọwọ-lọwọ.

Bẹni ọpọlọpọ enia ti o mu moto ayọkẹlẹ lọ si ba Ọba to bẹ wọ inu Iga rẹ pẹlu orişirişi ilu, orin ati ijo, inu Ọba ra si dun fun ẹyẹ ti awọn ara ilu se fun o si ki nwọn ku ile pẹlu ọpẹ.

# AWOLOWO LO SI KAMERUU



NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ karun oşu karun ọdun yi ni Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Action Group ba ọkọ ofurufu fo lọ si Kamẹrun (Cameroons) fun pipe ti awọn Ẹgbẹ oṣelu ibẹ Kamerun National Congress pe e lati wa bẹ awọn wo.

Awọn ẹmẹwa rẹ (awọn marun) ti nwọn jẹ mẹmba Ẹgbẹ Action Group ti nwọn ba a lọ ni Ayọ Rosiji, M.A. Ogun, Alfred Rewane, H.A.B. Fasinro ati Ademiluyi, awọn mararun na ni o wa pẹlu Ọlọla Obafẹmi Awolọwọ ninu aworan oke yi. Alọ a dara, abọ asunwọn.

## Ilori Pabi-Ekun Je Oye Babasanya

EDUNABON:- Ni ọjọ kejilelogun oşu keji ọdun yi ni Ọgbẹni Ilọri Pa-bi-ẹkun Oloye Olukosi pẹlu awọn ẹbi rẹ de si ile Balẹ ti'lu ti'fon fun ijawelelori oye.

Balẹ Adeyẹmi joko lori aga, awọn Ijoye ati awọn bale joko yika rẹ, nigbana ni Balẹ pe Ijoye Olukọtun Adewumi pe ki o fi ewe oye le e lori ati pe ki o kunlẹ niwaju Balẹ, ki iṣe aṣa iṣẹdalẹ wọn pe, ẹniti o ba ja ewe oye le lori ni lati joko lori aga, bikoṣe ni ikunlẹ niwaju Balẹ.

Balẹ bere lọwọ awọn ẹbi rẹ pe inu wọn dun si i bi? Nwọn si wipe o tẹ awọn lọrun; nwọn si fi ewe oye le e lori pe, ki o fi ọwọ ọtun rẹ le e, pe on jẹ oye Babasanya loni, ati pe ki o fi ọwọ osi le apakan pe on bọ oye Olukosi sile lati onilọ.

Nwọn tun wu oye yi jade ni, nitoripe nwọn ti jẹ oye na sẹhin mọ to ọdun mẹtadilogoji (37 years). Oloye Ilọri ṣe dada nigbati o ti jẹ oye Olukosi fun ọdun mẹrindilogun (16years).

O si fi ijo ati ayọ pada si ile rẹ, awọn ẹbi rẹ si nkọrin pe "Amoye yi jẹ iwo npa iwo ngna."

Awọn diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn ẹbi rẹ ni:- Ọgbẹni J. Oguntọna, J. Akinrinọla, Abẹṣẹ, Alexander Ogundele, Dan Anwo, Johnson Salakọ, awọn Oloye ti o ba a wa ile ni: Adewumi Olukọtun, Akintoye Logun, Awoyẹmi Otun, Deborah Ẹgbẹfunkẹ, Iyalode, Eli Ẹgbẹfunkẹ Otun, Maria Oni Osi, Odunlami, S. Akinrẹfọn.

Oloye na si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ rẹ lọrun. Awọn ọmọ Oloye na ni:- Ige, Rachel Seloia ati awọn aburo wọn. Oye a mọri o. [Idile Osifila].

PR-GRESS

O! ARE U MISSING

16 hours of it for less than

3D A DAY---GET REDIFF-SION

